NHS

# HPV

## vaccination

Dídàbòbò tako ìkóràn HPV láti ràn ọ́ lọ́wọ́ láti dín ewu ààrùn jẹjẹrẹ rẹ kù



arm against cancer

## Ètò gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára gbogbogbò

Abẹ́rẹ́ àjẹsára HPV náà ni a ti fún gbogbo àwọn ọmọbìnrin ọlọ́dún 8 tó wà ní ilé-ìwé lati osù Kẹsan ọdún 2008. Lati osù kẹsan ọdun 2019 a ti fun awọn ọmọkunrin ọmọ ọdun 8 ni abẹrẹ ajẹsara

Èyí ni wípé ẹ̀rí náà f'ojú hàn kedere pe abẹ́rẹ́ àjẹsára HPV ń ṣèrànwọ́ lati dábòbò àwón ọmọkùnrin àti ọmọbìnrin lọ́wọ́ àárùn jẹjẹrẹ tí HPV ńfà.

**Abẹ́rẹ́ àjẹsára HPV tó ju mílìònù 280 lọ ni a ti fún àwọn ènìyàn l'ágbàáyé, èyítí ó pẹ̀lú abẹ́rẹ́ àjẹsára mílìònù 120 ní orílẹ̀-èdè US àti ju mílìònù 10 ní orílẹ̀-èdè UK.**

### Abẹ́rẹ́ àjẹsára HPV ń ṣèrànwọ́ lati dábòbò ọ́ lọ́wọ́ kíkó àárùn human papillomavirus (HPV).

Àárùn yìí ń mú kí ewu níní jẹjẹrẹ l'ọ́jọ́ iwájú gbèrú síi, bí i:

- jẹjẹrẹ oju-ara
- àwọn jẹjẹrẹ ẹnu àti ọ̀nà ọ̀fun
- àwón jẹjẹrẹ ihò ìdí àti agbègbè ojú ara

Abẹ́rẹ́ àjẹsára HPV kò dábòbò tako àwọn ìkóràn àárùn ìbálọ̀pọ̀.



## HPV àti bí ó tí ńràn sí

**Ìkóràn HPV wọ́pọ̀.** Ju ìdá àádọ̀rin nínú ọgọ́rùn-ún (70%) àwọn ènìyàn tí kò tíì gba abẹ́rẹ́ àjẹsára ni yoo gbàá

70%

**HPV ńgbé lórí ẹran ara tó wà nínú àti l'ayika gbogbo oju-ara**, nítorí náà lílo àwọn ọ̀rá ìdábòbò kò pèsè ààbò tó kún lọ́wọ́ HPV

Àwọn **ọ̀pọ̀ orisirisi irú** HPV ló wà

Ọ̀pọ̀ àwọn ààrùn HPV kìí fa àwọn ààmìn ààrùn kankan wọ́n sì má ń **sàn fúnra wọn**

**Àwọn kan kìí pajúrẹ́** wọ́n si le yọrí sí ààrùn jẹjẹrẹ nígbàtí àwọn ìyókù nfa wọ̀nwọ̀n ojú ara

## Ìyàtọ̀ wo ni Abẹ́rẹ́ àjẹsára HPV ti ṣe?

Ọdún mẹwa lati ìgbàtí ètò abẹ́rẹ́ àjẹsára ní orílẹ̀-èdè UK ti bẹ̀rẹ̀ ẹ̀dínwọ́ ńlá ti wà ní kíkó ààrùn HPV àti nínú iye àwọn ọ̀dọ́ tóní wọ̀nwọn ojú ara.

Níbàyí a ní ìrètí pé abẹ́rẹ́ àjẹsára náà yóò dábòbò ọ̀pọ̀ ọgọrun ẹ̀mí l'ọdọọdun ní orílẹ̀-èdè UK.

**Làti fún ọ ní ààbò tó dàra jùlọ, o gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsara náà saájú k'otó máa ní ìbálòpọ̀ dáradára.**

**Bí o bá tí ń ní ìbálòpọ̀ dáradára o sì gbọ́dọ̀ gba abẹ́rẹ́ àjẹsara náà.**

## Gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára HPV

Awọn abẹ́rẹ́ àjẹsára naa ni a fún ọ gẹgẹbi abẹ́rẹ́ sí oke apa rẹ.

Ọ̀pọ̀ ènìyàn yóò nílò abẹ́rẹ́ kan láti l'ààbò. Èyí ni a nsaba fúnni ni akoko ti o ba wa ni ọdún ẹ̀kọ́ 8.



## Abẹ́rẹ́ àjẹsára HPV

Abẹ́rẹ́ àjẹsára HPV ti a lo **ninu àlàkalẹ̀ ètò gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsára NHS** jẹ́ Gardasil 9 o sì l’áàbò tako irú àwọn HPV tí o le fa ààrùn jẹjẹrẹ àti àwọn ohun wúwú ojú ara fún ọ̀pọ̀lọpọ̀ ènìyàn pẹ̀lú abẹ́rẹ́ kan péré.

## Mo pa abẹ́rẹ́ àjẹsara jẹ, ǹjẹ́ mo sì le gbà á?

Bẹẹni. Bí o bá pa ọ̀kankan nínú àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsara ní ilé-ìwé jẹ, o gbọ́dọ̀ gbìyànjú láti gbà á láìpẹ́.

Kàn sí nọ́ọ̀sì ilé-ìwé rẹ, ikọ̀ abẹ́rẹ́ àjẹsara ilé-ìwé rẹ tàbí asiṣẹ́ GP láti sètò ìpàdé kan.

O le yege láti gba abẹ́rẹ́ àjẹsara títí ó fi pe ọmọ ọdun 25.

## Àwọn obìnrin tí wọn ti gba abẹ́rẹ́ àjẹsara yó sì nílò láti lọ fún àyẹ̀wò ojú-ara.

Gbogbo àwọn obìnrin tó jẹ́ ọmọ ọdún 25 sókè ni orilẹ ede England ni a fún ni àwọn àyẹ̀wò ojú-ara. Abẹ́rẹ́ àjẹsara HPV náà yóò dènà tó ìdá aadọrun nínú ọgọrun-un (90%) ìsẹ̀lẹ̀ ààrùn jẹjẹrẹ, sùgbọ́n àwọn obìnrin gbọdọ sì lọ fún àyẹ̀wò ojú-ara nígbàtí wọ́n bá ní kí wọ́n ṣe bẹ́ẹ̀.



### Ti àwọn ààrùn jẹjẹrẹ yòókù ńkọ́?

Kòsí àwọn ètò àyẹ̀wò lọ́wọ́lọ́wọ́ fún àwọn ààrùn jẹjẹrẹ mìíràn tí HPV nfa. Bí ò bá ń s’àníyàn nípa àwọn ààmìn ààrùn kankan bá asiṣẹ́ GP rẹ sọ̀rọ̀.

### Àwọn ìdíjú

Gẹ́gẹ́bí ọ̀pọ̀lọpọ̀ àwọn abẹ́rẹ́ àjẹsára yòókù, àwọn ìdíjú gbígba abẹ́rẹ́ àjẹsara kò le rárá. Egbò, wúwú àti pípọ́n nínú apá wọ̀pọ̀ sùgbọ́n yóò yọ́ kúrò ní àìpẹ́ ọjọ́. Ọpọlọpọ awọn idiju to le ko wọpọ.

Abẹ́rẹ́ àjẹsára ti kọja awọn odiwọn to le fun ilo ni orilẹ-ede UK o si ti s’afihan lati jẹ abẹrẹ to l’aabo gidigidi. Miliọnu abẹ́rẹ́ àjẹsára ni a ti fun awọn ọmọkunrin ati ọmọbinrin ni orilẹ-ede UK ati ni gbogbo agbaye. Gẹgẹbi gbogbo abẹ́rẹ́ àjẹsára, awọn eyikeyi ijabọ ni a ti mojuto ati s’ayẹwo daradara.

O le jábọ̀ àwọn ìdíjú tí o furasi lórí ojú-ewé káádì Yellow (Yellow Card) tàbí nípa pípe **0800 731 6789** (agogo 9 òwúrọ̀ si 5 ìrọ̀lẹ́ Ọjọ́ Ajé sí Ẹtì) tàbí nípa gbígba ápùù Yellow Card sílẹ̀ sórí ẹ̀rọ.

**www.mhra.gov.uk/yellowcard**

# Rántí

- láti gba abẹ́rẹ́ àjẹsara nísisìnyí, láti dàbòbò ara rẹ tako àwọn ààrùn jẹjẹrẹ kọọkan ní ọjọ́ iwájú
- níbàyí a ní ìrètí pé abẹ́rẹ́ àjẹsára náà yóò dábòbò ọ̀pọ̀ ọgọrun ẹ̀mí l'ọdọọdun ní orílẹ̀-èdè UK
- koda pẹlu aabo lati ọdọ abẹrẹ ajẹsara HPV o si ma nilo awọn ayẹwo ilera, bii ayẹwo oju ara lati ọmọ ọdun 25

## Fún ìwífún síi, ṣe àbẹ̀wò sí www.nhs.uk/hpv

Akojọpọ awọn eronja to pe fun abẹrẹ ajẹsara Gardasil 9 ni a pese ninu Iwe pelebe Iwifun Alaisan (PIL):
**www.medicines.org.uk/emc/product/7330/pil**

Àkópọ̀ ti Orísìí Ẹ̀dà Ọjà (SPC):
**www.medicines.org.uk/emc/medicine/7330**

NHS HPV ACTION.ORG

Ìwé pélébé yìí ni a ti pèsè láti ọwọ́ Àjọ Àbò Ìlera UK (UK Health Security Agency).
**Immunisation, helping to protect everyone at every age.**

O le beere fun tabi gba iwe pelebe naa sori ẹrọ rẹ lati: www.healthpublications.gov.uk, nipa pípe: 0300 123 1002 (Agogo 8 owurọ si 6 irọlẹ, Ọjọ aje si Ẹti).
Ìwé pélébé yìí wà ní ìtumọ̀ sí àwọn èdè wọ̀nyí: Albanian, Arabic, Bengali, Brazilian Pt., Bulgarian, Chinese, Spanish, Estonian, Farsi, Fijian, Greek, Gujarati, Hindi, Kurdish, Latvian, Lithuanian, Nepali, Panjabi, Pashto, Polish, Romany, Romanian, Russian, Somali, Tagalog, Turkish, Twi, Tigrinya, Ukrainian, Urdu, Yiddish ati Yoruba

© Crown Copyright 2023. Product code: HPVU1L-YO. 3P 850K MAY 2023 (APS)
UK Health Security Agency gateway number 2023-050 Yoruba